# NADABU ATI ABIHU

## Lefitiku 10:1-20; Numeri 3:1-4

## ẸKỌ 85 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "A o yà mi simimọ́ ninu awọn ti nsunmọ mi, ati niwaju awọn enia gbogbo li a o yìn mi li ogo" (Lefitiku 10:3).**

**I Ikú Aipé ọjọ awọn Ọmọ Aarọni Meji ti o Dagba ju lọ**

1. Ọlọrun ya Aarọni ati iran rẹ sọtọ lati wà ni ipò alufaa ni Israẹli, Numeri 3:1-3; Ẹksodu 28:1; Numeri 18:1-7
2. Iwa afojudi ati aigbọran ti Nadabu ati Abihu hù mú ki iná wá lati ọdọ Oluwa, o si pa wọn, Numeri 3:4; Lefitiku 10:1, 2; 1 Samuẹli 6:19; 2 Samuẹli 6:6, 7; 2 Kronika 26:16-23; Matteu 21:12, 13; Deuteronomi 4:24; 9:3; Heberu 12:29
3. Mose rán Aarọni baba wọn leti Ofin Oluwa ti o wi pe Oun ni lati gba ọla ati ogo, Lefitiku 10:3; 1 Samuẹli 2:17; Ẹksodu 34:14; Orin Dafidi 73:28; Heberu 10:22; Jakọbu 4:8
4. Awọn ọmọ Lefi meji ti idile Kohati, ibatan awọn ti o kú, ni wọ́n fun laṣẹ lati gbé awọn oku naa jade kuro ninu agbala Agọ ki a ma ba sọ awọn alufaa ti wọn n ṣiṣẹ isin di alaimọ́ tabi ki o ma ba di wọn lọwọ ninu iṣẹ iranṣẹ wọn, Lefitiku 10:4, 5; 21:1-6, 10-12; Numeri 3:19, 27-32
5. Mose rán Aarọni ati awọn ọmọ rẹ ti o kù leti pe jijẹ oloootọ si Ọlọrun ati si iṣẹ Oluwa tobi ju iṣẹkiṣẹ tabi ojuṣe ti a ni lati ṣe fun eniyan lọ, Lefitiku 10:6, 7; Matteu 6:33; 1 Awọn Ọba 19:19-21; Luku 9:59-62
6. Aarọni, Eleasari ati Itamari fi igbọran di ipo wọn mú, Lefitiku 10:3-7; Marku 10:28-30
7. Ọlọrun tikara Rẹ paṣẹ fun Aarọni ati awọn ọmọ rẹ lati ya ara wọn sọtọ fun Oluwa ki wọn ba le sin In bi o ti yẹ, Lefitiku 10:8-11

**II Ipari Iṣẹ Isin ti Ọjọ Naa**

8. A paṣẹ fun awọn alufaa lati maa bá isin irubọ lọ ati lati jẹ ninu ẹbọ ohun jijẹ ti a pese silẹ fun wọn ni Ibi Mimọ́, Lefitiku 10:12, 13; 9:4
9. Igẹ̀ ati apa ẹran fun ẹbọ alaafia ni ki awọn alufaa ati idile wọn jẹ ni ibi mimọ́ kan, Lefitiku 10:14, 15; 9:4, 18-21; Numeri 18:8-20
10. Mose ri i pe awọn alufaa ko ti i jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ awọn eniyan naa, o bá awọn ọmọ Aaarọni wí fun ikuna wọn, Lefitiku 10:16-18; 9:3, 15, 22; 6:30
11. Igbẹjọrò ti Aarọni ṣe fun awọn ọmọ rẹ ti a bawi fi hàn pe ẹ̀rù ba a pe awọn ọmọ naa ko i ti i ya ara wọn si mimọ́ (nitori naa wọn kò yẹ lati jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ naa), laisi aniani, nitori idajọ ojiji ti Ọlọrun mu wá ni ọjọ naa nitori ẹ̀ṣẹ ikugbu, Lefitiku 10:19, 20; 9:15-17

## ALAYE

**Idajọ Ojiji laaarin Ibukun**

Agọ Ajọ, nigba ti a ri i kẹyin, kún fun ogo Ọlọrun, awọn eniyan si n fi tayọtayọ, ati tọwọtọwọ jọsin, eyi ti o fi iyọ́nú Ọlọrun si awọn eniyan Rẹ hàn. A ri idasilẹ ipò oyè alufaa ti Aarọni ati ifiwera ti o wà laaarin rẹ ati ipo oye alufaa ti Kristi, Ẹni ti O n ṣe Alagbawi fun wa nisisiyii (1 Johannu 2:1). Ṣugbọn ẹni kan ti wi pe "Bi a ba kọ imọlẹ, okunkun biribiri a ṣú bo ni," a si le ri ifarahan otitọ naa ninu ẹkọ yii, nitori nigba ti ogo Ọlọrun fi ara hàn ninu ati ni ayika Agọ Ajọ ti a ṣẹ̀ṣẹ̀ yà si mimọ́, ikuuku idajọ ojiji sọkalẹ wá ti o yọri si ikú ati ibanujẹ.

Iru igbẹsan bayii jẹ́ apẹẹrẹ ibinu Ọlọrun ti yoo mú iparun bá gbogbo awọn ti wọn ro pe wọn n sin Ọlọrun, ṣugbọn ti wọn kò gba ọna ti Ọlọrun la silẹ, ti i ṣe nipa Etutu Ẹjẹ Kristi. Ibinu Ọlọrun maa n wà nibikibi ti ẹ̀ṣẹ bá wà: ṣugbọn o maa gbona girigiri ju lọ nibi pẹpẹ mimọ́ Rẹ bi awọn ti o wà nibẹ ba fi aigbọran ati ọwọ́ aimọ́ ba iṣẹ isin Rẹ jẹ́.

Ina ti Ọlọrun fẹ lo fun sisun turari ti sọkalẹ lọna iyanu sori pẹpẹ idẹ, awọn alufaa ti n ṣiṣẹ isin si mu ki o maa jó nigba gbogbo (Lefitiku 6:12, 13). Lẹyin ti o ti kú siwaju tabi ni akoko ogun ti o wà laaarin Saulu ati Dafidi, a tun da a pada nigba iyasi mimọ́ Tẹmpili Sọlomọni, gẹgẹ bi o ti ri gan an nigba ti a kọ́kọ́ fi fun wọn. Turari, ti yoo ṣe itẹwọgba fun Ọlọrun, ni eyi ti a ṣe gẹgẹ bi itọni Oun tikara Rẹ ti a si n lò fun iṣẹ isin Rẹ nikan ṣoṣo. Bi eefin rẹ ti i ṣe apẹẹrẹ adura bá goke lọ lati inu eedu iná mimọ́ naa, eyi tọka si pe o ṣe itẹwọgba. Awọn eniyan wọnyii mọ̀ pe Ọlọrun ko ni tẹwọgba isinkusin kan ayafi eyi ti o ba ni imisi lati ọ̀dọ̀ Rẹ, ṣugbọn wọn kọ eti didi si gbogbo eto ati itọni Rẹ.

Nadabu ati Abihu ki i ṣe eniyan lasan. Ọmọ olori alufaa Israẹli ni wọn n ṣe, ọmọ ẹgbọn alakoso Israẹli, ati aṣiwaju awọn agbaagba Israẹli. Wọn ti wà pẹlu Mose ati Aarọni lori oke Ọlọrun, wọn ti ri iran ogo Ọlọrun bi o ti fara hàn ni Sinai; a ti yàn wọn, a si yà wọn sọtọ fun oyè alufaa, wọn si ti bá Aarọni ṣiṣẹ pọ̀ ni ibi irubọ ekinni. Ṣugbọn pẹlu gbogbo eyi, wọn tabuku si ohun mimọ́ Ọlọrun, idajọ bi ajonirun iná si ti ọdọ Oluwa wá o lù wọ́n pa. Wọn ti ipo giga "gbajumọ" ṣubu sinu ọfin iparun.

Nadabu ati Abihu jẹ́ alufaa ti a tẹwọ gbà ni owurọ, wọn si di ẹni ti iná ibinu Ọlọrun parun ni aṣaalẹ. Kò i ti pé odindi ọjọ kan, bẹrẹ lati owurọ, ti ijọ eniyan sun mọ Nadabu ati Abihu gẹgẹ bi ẹni mimọ́ Oluwa, lai pẹ titi ti wọn si tun fi iwariri fà sẹyin kuro lọdọ wọn gẹgẹ bi ẹni ègún Ọlọrun. Ni owurọ wọn ni ireti ọjọ ologo niwaju wọn, ṣugbọn ni aṣaalẹ ikú le wọn bá, gbogbo ireti wọn si parẹ̀. Orisun ati olori ẹṣẹ awọn ọmọkunrin wọnyii ni pe wọn kùgbu ṣe ifẹ inu ara wọn, wọn ko naani "Bayi ni OLUWA wi."

Nigba ti a beere lọwọ eniyan mimọ Ọlọrun kan pe, “Ki ni ohun ti o lewu ju lọ ti eniyan le ṣe?” O dahun pe, “Lati fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mu Ọrọ Ọlọrun, ati lati gbé ara ga.” Ọlọrun fi hàn wa gbangba nihin pe Oun ki yoo gbà bẹẹ pe ki igbekalẹ eniyan dipo ilana isin ti Rẹ̀. Ẹni ti o ba fi ohun miiran dipo bẹ́ẹ̀, n gbé ara rẹ ga si Ọlọrun ni, o si daju pe ẹni naa kò ni wà lai jẹbi niwaju Ọlọrun. Itanṣan imọlẹ lati ọdọ Ọlọrun le fọ́ irú ẹni bẹẹ loju; apoti Majẹmu Ọlọrun le pa a run; ibi mimọ Ọlọrun le lu u bolẹ; tabili Oluwa le sọ ọ di ẹni idalẹbi. Ododo Ọlọrun ti eniyan mọọmọ̀ yipo le di ẹwọn irin ti yoo de ẹni aladamọ̀ bẹẹ mọlẹ, ki o si bu ifọju lù ú laelae.

Ọlọrun le maa ba iṣẹ Rẹ̀ lọ pẹlu iwọnba awọn olooótọ diẹ, ṣugbọn ko ni nnkan kan ṣe pẹlu ọpọlọpọ awọn alaimọ́ eniyan ninu aṣọ oyè alufaa ti wọn n sin ifẹkufẹ ọkàn wọn. Ọrọ kan sọ pé, “Aiṣootọ nibi pẹpẹ yoo bi isinkusin ninu agọ.” Ẹgbẹ alaimọ́ alufaa ko le kọ́ eniyan ni iwa mimọ́ lati sọ ọ di olododo ti yoo fi le jogun ini Ọlọrun. Isọkalẹ ibinu Ọlọrun sori awọn ọmọ Arọni wọnyii n tẹnu mọ ọn fun wa gbọnmọ gbọnmọ pe, “Ẹ jẹ mimọ́, ẹnyin ti ngbe ohun-èlo OLUWA” (Isaiah 52:11).

**Ijolootọ Aarọni**

Ni ori kẹwaa ẹsẹ̀ kẹta Lefitiku, gbolohun kan wà nibẹ ti o ni iwọnba ọrọ diẹ, ṣugbọn ẹyọ ọrọ diẹ wọnni kún fun itumọ ti o jinlẹ gidigidi: “Aarọni si dakẹ.” Ọgbẹni yii duro jẹẹ, o si n wo oku awọn ọmọ rẹ meji ti o dagba ju lọ nilẹ bayii ninu ibi-mimọ́, nibi ti ibinu Ọlọrun gbé lù wọn pa si. Kò si itunu kan fun un ni wakati ọ̀fọ naa, ayafi ti pe o jẹ amuwa Ọlọrun, lati fi iwa mimọ́ ati ogo Rẹ hàn. O mọ pe iyà ti o tọ́ si wọn ni, sibẹ, inu rẹ̀ kò le ṣai bajẹ gidigidi gẹgẹ bi baba ti o ni ifẹ si ọmọ rẹ̀. Pẹlu gbogbo ibanujẹ ati ẹ̀dùn ọkan rẹ,. o “dakẹ” jẹẹ.

**Ofin nipa Oku**

O dara bẹẹ pe ki awọn olori idile Kohati ninu ẹya Lefi, ti wọn o maa ṣe ipalẹmọ awọn ohun-elo mimọ ati ohun ọṣọ inu Agọ lai pé, gbé oku awọn ọkunrin wọnyii kuro, awọn ti a dalẹbi ikú. Elsafani jẹ́ olori idile awọn Kohati, Miṣaeli si jẹ́ arakunrin rẹ̀, oun naa pẹlu, lai si aniani, si ni ipò giga ninu iṣẹ isin awọn ọmọ Lefi.

A kà pe lẹyin naa nigba ti akoko ikú Aarọni sunmọle, Oluwa paṣẹ pe ki a bọ́ ẹwu oye alufaa rẹ̀ kuro lara rẹ̀ nigba ti o si wà laaye, ki a si fi i fun atẹle rẹ̀. Bi o ba lọ ku pẹlu awọn aṣọ iyasọtọ wọnyii lara rẹ, yoo jẹ pe aṣọ wọnni ko ni ṣe e lo mọ́ ninu ibi mimọ́ (Numeri 20:26). Ṣugbọn idajọ Ọlọrun lori awọn alaiṣootọ alufaa wọnyii yara de to bẹẹ ti ko fi si akoko lati bọ́ aṣọ oye wọn kuro lara wọn. Wọn kú ninu aṣọ naa, ati nitori idibajẹ ti wọn ti mu ba a, a kuku sin Nadabu ati Abihu pẹlu aṣọ oye wọn. Iṣẹlẹ yii ni Juda n tọka si ninu Episteli rẹ̀ bayii pe: “Ẹ mã fi ẹ̀ru gba awọn ẹlomiran là, ẹ mã fà wọn yọ kuro ninu iná; ẹ tilẹ mã korira ẹ̀wu ti ara ti sọ di ẽri” (Juda 23).

Mose tún rán awọn alufaa ti o kù leti nipa awọn ikilọ miiran ninu Ofin. Wọn ko gbọdọ fi hàn pe wọn n ṣọfọ nitori wọn n ṣiṣẹ ni ibi mimọ́. Awọn ti o ba n ṣe iru iṣẹ bẹẹ ni lati sá fun ohunkohun ti yoo sọ wọn di alaiyẹ fun iṣẹ yii (Johannu 4:31-36). Siwaju si i, nitori ẹ̀ṣẹ naa buru niwaju Ọlọrun to bẹẹ gẹẹ ti ibanujẹ tabi ọfọ le mu ki eniyan ro pe Ọlọrun jẹbi lati hu iwa onroro bẹẹ.

**Iṣẹ-isin Ọlọrun Bẹrẹ Lọtun**

O fẹrẹ jẹ pe akoko ti a fi royin iṣẹlẹ buburu naa gun pupọ ju akoko ti a lò lati mu idajọ naa ṣẹ. Awọn arufin naa wá siwaju Ọlọrun, sinu Ibi Mimọ a si ké wọn lulẹ. Awọn alufaa iyoku duro pẹlu ibẹru nitori idajọ ti a múṣẹ nigba ti Mose alakoso sọ fun wọn bi wọn yoo ṣe gbé oku wọnni kuro, o si fun wọn ni ikilọ pẹlu. Lẹyin eyi awọn alufaa gba aṣẹ lati tun bẹrẹ iṣẹ isin Ọlọrun, wọn si n bá iṣẹ irubọ wọn lọ gẹgẹ bi ti atẹyinwa.

Nigba ti a ba mu ọrẹ ẹbọ kan wa fun Oluwa, awọn alufaa yoo jẹ apa kan rẹ̀. A ti fi hàn fun ni pe nigba ti wọn ba jẹ ti wọn tan, nnkan miiran tun wà ju jijẹ lasan lọ fun imudagba ti ara. Bi awọn alufaa ti n jẹ ọrẹ ẹbọ wọnyii, wọn jẹ́ apẹẹrẹ akoko ti ati alufaa ati ẹbọ yoo jẹ ẹni kan: Ẹni naa ni Jesu Kristi, Messiah. Jijẹ ounjẹ yii jẹ́ apa kan iṣẹ isin irubọ, wọn kò si gbọdọ ṣe e pẹlu aikiyesara, aironu tabi ailọwọ. (Ka 1 Kọrinti 11:23-30).

Awọn ẹbọ miiran wà ti awọn alufaa nikan ni lati jẹ ninu Ibi Mimọ́, awọn miiran si wa fun awọn ara ile alufaa, wọn si le jẹ ẹ ni ibi ti o mọ́ kan lẹyin Agọ. Sibẹ ẹbọ ẹṣẹ ti a gba ẹ̀jẹ rẹ̀ lọ si Ibi Mimọ́, ti a si ta á sori pẹpẹ wura ati si iwaju aṣọ ikele ki i ṣe jijẹ. A gbọdọ sun ẹran irubọ naa lẹyin ibudo nibi ti o mọ́ tonitoni.

**Ẹbọ Ẹṣẹ ti Wọn Kò Jẹ**

Mose tete kiyesi i pe aṣiṣe miiran tun lè ṣẹlẹ; o fi itara ti olori tootọ boju to gbogbo iwa awọn alufaa naa lati ri i pe wọn ṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun (Heberu 13:17). Oun ni o fi eto irubọ kọọkan lelẹ finnifinni.

Niwọn bi wọn ko ti mú ẹ̀jẹ ẹran irubọ ẹ̀ṣẹ awọn eniyan lọ si Ibi Mimọ́, awọn alufa ni lati jẹ ẹran naa (Ka Lefitiku 6:24-30). Nigba ti Mose ri i pe wọn kò ṣe bẹẹ, o bá awọn ọmọ Aarọni meji iyoku wí fun sisun ti wọn sun ẹran naa dipo ki wọn jẹ ẹ. Aarọni bẹbẹ fun awọn ọmọ rẹ̀, Mose si gba ẹbẹ rẹ̀ nitori ibi ti o ti ṣẹlẹ ni ọjọ naa. Ohun ti ẹbẹ rẹ̀ duro le lori ni pe awọn ti ṣe ohun gbogbo tọwọtọwọ ti o yẹ ni ṣiṣe nipa ti irubọ yii; afi eyi ti o jẹ mọ ti ohun jijẹ. O wi pe, “Irú nkan wọnyi li o ṣubu lù mi; emi iba si ti jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ li oni, o ha le dara li oju OLUWA” Eyi fi hàn pe ibanujẹ tí idajọ gbigbona yii mú bá Aarọni ni o mu ki o yẹ ọkàn ara rẹ̀ wò lati ri i pe oun kò ṣe aigbọran si ofin Ọlọrun.

Boya awọn alufaa iyoku naa kò jẹ ninu ẹbọ naa, nitori wọn rò pe wọn ṣe alaiyẹ, wọn si n bẹru pẹlu lati ṣe ohun ti kò tọ́ ti yoo si fa idajọ wá si i. Ami ororo Oluwa wà lori wọn, ṣugbọn wọn le ro pe wọn jẹ́ alaimọ́ lọna kan bi wọn ti ri ifarahan agbara Ọlọrun ti o ba ni lẹru (Isaiah 6:1-5). Wọn ro pe boya awọn le jẹ ẹbọ ti iyin ti i ṣe ipin ti wọn lai si ifoya; ṣugbọn nigba ti o di ti jijẹ ninu irubọ eyi ti wọn mú wá lati wẹ ẹ̀ṣẹ abinibi awọn eniyan nù, eyi jẹ ohun ti o lewu pupọ, wọn kò si fẹ kùgbù ṣe ohun bẹẹ.

**Ohun ti Iṣẹlẹ yii Kọ́ Wa**

A ri ẹkọ kan ti o ba ni lẹru kọ́ ninu itan igbesi-ayé awọn eniyan Israẹli yii. Fun olododo, ikú ojiji jẹ́ idande ojiji kuro lọwọ gbogbo inira ayé yii. Bibọ́ sinu Ogo ojiji ni o já sí fun irú ẹni bẹẹ. O gba a kuro lọwọ ọpọlọpọ aniyan ati irora. O sọ ara kiku rẹ̀ di aikú titi lae. O yọ ọ kuro ninu afonifoji omije ati ibanujẹ, o si gbe e lọ si ilẹ ayọ̀ ati alaafia titi ayé. Iru ipò ti ẹni naa wà ni a ti yanju titi ayeraye, nitori a ki i dẹṣẹ ni Ọrun, kò sì sí oludanwo nibẹ lati sún un dẹṣẹ.

Ṣugbọn nigba ti a ba ke alaironu ati alagidi ẹlẹṣẹ kuro ti a si mu un lọ si idajọ airotẹlẹ, ohun ẹ̀ru gidigidi ni o jẹ́. Bi o ba ri bẹẹ ko si anfaani lati ṣe atunṣe tabi ironupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀. Ibi ti igi ba wó si, ibẹ naa ni yoo si wà titi (Ka Oniwasu 11:3). Kò si bi o ti wu ki eniyan jẹ́ olufọkansin tó, ipò rẹ̀ nipa ti ẹmi lakoko ikú ni yoo sọ ibi ti yoo wà titi ayeraye. Kò si àye mọ́ lẹyin ikú lati ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ tabi lati ri iwẹnumọ ẹ̀ṣẹ. Bi a ti lo ayé wa sí bẹẹ naa ni a o kú -- ni iru ipo bẹẹ ni a oo si duro niwaju Ọlọrun.

Nadabu ati Abihu ti jẹ́ olufọkansin iranṣẹ Ọlọrun tẹlẹ, wọn si ti gbadun anfaani pupọ ti a kò fi fun ọpọlọpọ ni Israẹli. Ṣugbọn wọn dẹṣẹ, bi wọn si ti wà ninu irekọja naa lọwọlọwọ, iná sọkalẹ o si sọ wọn di òkú lẹsẹ kan naa. Wọn kò ni duro niwaju Ọlọrun ni ọjọ idajọ gẹgẹ bi olufọkansin ti o ri ogo Ọlọrun lori Oke Sinai, bi kò ṣe gẹgẹ bi ọlọtẹ, aṣetinu-ẹni, ẹlẹṣẹ, agberaga, ti wọn fi ọna ti wọn dipo eto Ọlọrun, awọn ẹni ti a si pè ninu aigbọran wọn lati wá duro niwaju Ọlọrun, ti a si da lẹbi nitori ẹ̀ṣẹ agidi ọkàn wọn (Owe 14:12).

## AWỌN IBEERE

1. Darukọ awọn ọmọkunrin Aarọni mẹrẹẹrin gẹgẹ bi ọjọ ori wọn.
2. Ki ni ohun pataki ti o mú akọbi ọmọ Aarọni yatọ si awọn iyoku?
3. Bawo ni awọn ọmọ wọnyii ti jẹ́ si Mose?
4. Sọ ohun ti awọn ọmọ meji wọnyii mọọmọ̀ ṣe ti o fa ikú wọn.
5. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi ọwọ́ danindanin mú iṣẹ isin Rẹ̀ bẹẹ?
6. Ki ni ṣe ti Aarọni kò fi le ṣọfọ wọn gẹgẹ bi baba ti gbọdọ ṣe nigba ikú awọn ọmọ rẹ̀?
7. Ki ni ẹkọ nla ti ihuwasi Aarọni kọ́ wa?
8. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fẹ ki iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀ jẹ́ mimọ́ ati ailabawọn?
9. Ki ni ṣe ti wọ́n gbé wọn sin pẹlu aṣọ oyè alufaa lara wọn?
10. Iru ẹbọ ẹ̀ṣẹ wo ni awọn alufaa le jẹ ni Ibi Mimọ́ ti wọn kò si gbọdọ sun lẹyin ibudo?